## Asayan Oro

Ewurę wo alapata, bi ki o ku. Awodi wo Igbin korǫ, Kini ẹiyẹ oko yio fi Igbin se ? Ori l'o nişe eda l'a yanmǫ.

# ELETI OFE

A-NJU-WỌN KO SE WI-L'EJO

## Akiyesi Pataki

A fiwe yi ş e ikede si awǫn Aşoju iwe irohin Eleti Ǫfe kakiri agbaiye wipe enikeni ti ko ba fi owo ti o ti je ranşe si wa, a o pe lejǫ, ako s ni fi iwe irohin ranşe si onibe mǫ.

VOL. XI No. 647. LAGOS. SATURDAY, OCTOBER 31 — NOVEMBER 6, 1959. KOBO MEJI (2d)

# N.C.N.C. Fi Meji Pere Tayo Action Group Ninu Igbimo Munisipa

Oju kakatikaka a ja, oju kakatikaka a ja, oju tikatika yio ja a lọpọlọpọ bi kinkin kọ. Ko si orin ti ale kọ si gbẹdu ayafi ero ya wa wo, n'ti ibo ti awọn ara ilu Eko di lọ yi fun Igbimo Munisipa (Lagos Town Council).

Awọn ẹ g b ẹ Action Group (Afẹnifẹre) ni ẹgbẹ ti o ti nşe alakoso ninu igbimọ yi wa lati ọdun kẹfa sẹhin, ti ilọsiwaju ati eto atata fun anfani ilu si ti nwọ ilu Eko.

Şugbọn, nisisiyi ẹ g b ẹ N.C.N.C. ni yio ma şe akoso fun igbimọ Town Council fun ọdun m ẹ t a gbako. Bi ojo ko tilẹ rọ, ti agbado ko gbo, oju takọ-tabo ni yio ja.

Iye awọn enia to wọle ninu ẹgbẹ Action Group ẹ 20 şugbọn ti ẹgbẹ N.C. N.C. jẹ 22, aye ti ko si ni ko j ẹ k i a to orukọ awọn enia ti o wọle na l'ẹsẹsẹ.

*Always ask for*

**'DE FACTO'**

*the bread with the appetising flavour*

### IYE OLOPA TI YIO ŞI ŞẸ NIGBA IDIBO NLA

Nigbati o ba di akoko idibo ninu oşu December ti o mbo yi awon olopa yio şe gudugudu meje ti ode nşe. Ni agbegbe Ila-Orun, ni Iwọ-Orun, ni Oke-Oya ati ni Eko. Iwonyi ni awon olopa ti yio wa lenu işe şulẹ ojo na.

| | |
|---|---|
| Awon Special Constable | 6,000 |
| Nigeria Police Force | 5,000 |
| Local Authority Police | 1,200 |
| Native Authority Police | 6,000 |

Ni ilẹ hausa, 174 enia ni nwon fẹ dibo yan 9,600, ni iye ibiti nwon o gbe apoti idibo si. Ni Ila-Orun, enia 73 ni awon fe dibo yan, 8,000, ni iye ibiti nwon o gbe apoti idibo si. Ni Iwo-Orun 62 enia ni afe dibo

(Wo yoku loju ewe keji)

# Ni iranti Oloye Bode Thomas



Awọn alaşẹ ebute Apapa (Nigerian Port Authority) kan ọkọ oyinbo ti ọju-omi kan ti nwọn şeşẹ gbe jade, oruko ti nwọn fun Ọkọ na ni "Bode Thomas" on ni ẹniti o kọkọ jẹ oye Alabojuto igbokegbodo ọkọ (Minister of Transport) nile Nigeria.

Nigbati nwọn pari kikan ọkọ na, nwọn fi iwe ipe ranşẹ si iyawo Ologbe na wipe ki o wa, fi ọla rẹ gbe ọkọ na jade soju omi, lẹhin na, nwọn pe apejẹ rẹpẹtẹ kan ti nwọn fi şe awowo ipa'nu ni iranti ologbe Oloye Bode Thomas.

Nibi ayẹyẹ yi, ọpọlọpọ enia l'o sọrọ iwuri nipa işe rere ti ologbe na şe nigba aiye rẹ, iyawo rẹ si sọrọ pelu omije loju wipe ọkọ on jẹ ọkan pataki ninu awọn ti o jijakadi fun ominira ile Nigeria, yio si jẹ didun inu on ti awọn alabaşepọ rẹ bale gbe iye na dori.

## THE NATIONAL BANK Of Nigeria Limited

Incorporated in Nigeria in 1938
Paid up Capital £1,130,000
Bankers to the Western Region Government of Nigeria
HEAD OFFICE
37, MARINA, LAGOS NIGERIA
22 Branches Throughout Nigeria including
IBADAN, ABEOKUTA, IJEBU-ODE,
OSHOGBO, OWO, ONDO, ILESHA,
ILARO, BENIN-CITY, WARRI,
SAPELE ABA, KANO, ZARIA, JOS

LONDON OFFICE

1 THROGMORTON AVENUE, E.C. 2.
Manager: F. O. Tyrrell.

Telephone: London Wall 4303
Cables & Telegrams Natbaniger London.

Head Office Representatives in London
E. Akinwunmi Doherty.
CORRESPONDENTS
NEW YORK, PARIS HAMBURG.

# Akoko Ise Ero Radio Nilu Oyinbo



Eniti a nwo ninu aworan yi, ni apa osi, ni Ọgbẹni O.T. Adedoyin ara ilu Shagamu nilẹ Nigeria, ti o lọ kọ iṣẹ ẹrọ Radio nilu Oyinbo, ẹnikeji rẹ ti o jẹ oyinbo ni orukọ rẹ njẹ L.D. Adams, on lo nkọ Adedoyin ni iṣẹ ẹrọ asọrọmagbesi. (Radio)






# THREAT OF STRIKE

The following statement is issued on the authority of the Federal Government:

1. The Trades Union Congress have announced that they propose to call upon their member unions, including those which represent Government staff, to come out on strike from or about the 1st of November, 1959, in connection with the Congress's demand for an interim award (on account of the general review of salaries and wages now proceeding) of 50o/o for daily paid workers and 3?o/o for junior salaried staff, effective from 1st of February, 1959.

2. The Federal Government is fully aware of the uneasiness felt by its established and unestablished employees about the present cost of living. As this matter affects officers and workers of the Federal Government stationed in localities throughout Nigeria, and represented by a wide variety of unions and staff associations a Commission for the review of wages and salaries has been appointed and will shortly make recommendations to the Federal Government and those Regional Governments which are associated with it in the review. In order to alleviate existing hardships, an interim award equal to 10o/o of the current basic rates of salaries and wages has been granted to salaries officers on the long scales (except certain highly-paid contract employees) and to daily paid workers. The purpose of the interim award is to grant interim relief, and award is therefore effective from the 1st September, 1959, until the Commission's recommendations have been received and decision on them is made by the Government. In view of the statistics available, and in view of the purpose for which the reviewing Commission has been appointed, the Federal Government considers both the amount and the effective date of its interim award to be eminently just and reasonable.

3. The Executive body of the Trade Union Congress was informed at all stages of Government's intentions with regard to the review of salaries and wages, and their goodwill was sought. The Congress was also informed that an interim award was contemplated and, since it had expressed views on this subject, was invited to explain its views. At all stages it has been made clear to the Congress however that, because the increased cost of living is a matter which affects all workers and all the unions which represent them, neither the general wage and salary levels which will result from the review nor the amount of the interim award can be made open to negotiation. Nor, even if negotiation were possible, could the Federal Government accept the Trade Union Congress as a competent body to negotiate on behalf of the Federal Government employees. In all matters properly subject to negotiation, the Federal Government will continue to act through the Whitley Councils which are the established joint negotiating bodies in respect of Civil Service conditions. The proper role of the Congress in the view of the Federal Government is that of adviser and guide to its constituent unions. It should not usurp the functions which are proper to the unions themselves.

4. With regard to the Trades Union Congress's threat of strike action on or after the 1st of November, all employees of the Federal Government are reminded that to come out on strike and to attempt thus to halt or dislocate the operations of the Government is a serious breach of discipline. Any who may contemplate going on strike, whatever kind of strike it may be, should understand clearly that :-

(a) they will receive no pay while they are on strike; and
(b) they will be liable to dismissal and to the forfeiture of any pension retiring allowance or gratuity for which they might otherwise be eligible.

# E DIBO FUN OPE

# SOJA AWON INDIA WA LAYE

Awon ara ilẹ India ti kebosi wipẹ awon ara ilẹ Şaina pa enia mẹtadilogun ninu Şoja won.

Şugbon awon ara ilẹ Şaina ranşẹ wipe awon şoja ti nwon wipe awon ti pa awọn koiti pa wọn, mimu ni awọn ara Şaina mu wọn.

Ati wipe awọn mesan ninu awọn [illegible] ,o wa ku şoja kan ti a şi nwa lọwọ-lọwọ yi.

---




Iye awọn ọmọ ti o nlọ si ile-ẹkọ [illegible] Ilẹ Ọrun Nijiria [illegible] lọdọdun. Awọn ọdọmọkunrin ati ọdọmọbinrin ti nlọ si ile-ẹkọ giga ni ọdun 1956 ni Ilẹ Ọrun Naijiria jẹ ọkẹ marun-din-logota o le ẹgbarun ati ẹrinladinirinwo (1,110,386). [illegible] ọkẹ mẹta ati ẹgbaje o din mẹdọgbọn ọmọ (70,375) ni o fi le si iye ti mbẹ ni ile-ẹkọ ni ọdun [illegible]. [illegible] iye awọn ọmọde ti o nlọ si ile-ẹko kekẹke ati ile-ẹko giga (secondary modern) [illegible].

Awọn ọmọde ti o nlo anfani ẹkọ [illegible] jẹ ọkẹ mọkanlelaadota ati ẹdẹgbasan o le ejila-dinirinwo (1,037,388), okunrin jẹ ọkẹ mejilelogbọn ati ẹgbẹrinla o le mẹrinlelogota (642,856), obirin si jẹ ọkẹ mọkandilogun ati ẹgbaje o le ojilelẹdẹgbẹta o din meji (394,532), eleyi si yatọ si ọkẹ mọkandiladọta ati ẹgbẹta o le ọtalelẹgbẹrin o din marun (982,755) ti nlo anfani na ni ọdun 1957. Awọn enia si tun nbere fun didasile ọpọlọpọ awọn ile-ẹkọ giga (secondary modern). Ọkẹ meji ati ẹdẹgbejọ o le meje (43,507) ni awọn ọmọ ti o wa ni ile-ẹkọ giga (secondary modern), ọkunrin jẹ ọkẹ kan ati ẹgbafa o le ọtalelẹgbẹrin ati mesan (32,869), obirin jẹ ẹgbarun ati ojilelẹgbẹta o din meji (10,638), eleyi si yatọ si ọkẹ kan ati ẹgbẹjọ o le meji iye ọmọ ile-ẹkọ ti o wa ninu ọdun 1957.

Awọn ọmọ ti o nlo si ile-ẹkọ giga (secondary grammar schools) jẹ ẹgbasan ati ẹdẹgbẹrin o le mẹrinlelaadọta (18,754) ọmọdekunrin jẹ ẹdẹgbajọ ati ẹgbẹrin o le mẹtadilọgọrin (15,877), ọmọbirin jẹ ẹgbẹrinla o le mẹtadilọgọrin (2,877); bẹni awọn ọkunrin ati obirin ti o nlọ si ile-ẹkọ giga ti a ti nkọ awọn olukọ (grade II) jẹ ẹgbaji ati mẹjidinladoje (4,128) ati pe awọn ti nkẹkọ ni ile-ẹkọ miran ti a si nkọ awọn olukọ (grade III) jẹ ẹgbẹtalelẹgbata ati mẹsan (6,009).

O fẹrẹ jẹ pe gbogbo awọn ile-ẹkọ ti o wa ni Ilẹ Ọrun ni Ijọba nran lọwọ. Ijọba ti nsapa rẹ lati dojukọ kikọ awọn olukọ ti yio kari gbogbo awọn ile-ẹkọ ti ngberu si. Ni ipari ọdun yi, awọn akẹkọ ti yio pari ẹkọ wọn lati ile-ẹkọ ti olukọ gbogbo yio jẹ ẹgbaji ati ọtalelẹdẹgbata o le mẹrinla (4,574), a si nireti pe nwọn yio mura lati se iṣẹ wọn gẹgẹ bi olukọ pataki ni awọn ile-ẹkọ gbogbo.

Ile Işẹ ti nkede-Ilẹ Ijọba Ilẹ Ọrun Naijiria l'ogbe ọrọ yi jade.

## KO ŞEKU KO ŞẸIYẸ AJAWO

Lati ọwọ R. Popoọla

O bẹrẹ ninu iwe ọsẹ to kọja

Nigbati ọmọ aguntan de ile, o ro ẹjọ fun iya rẹ bi adan ti şe huwa ika si on, o si fi gbogbo oru na kẹ "mẹ ẹ" nitori inu rirun ti o de si ọmọ aguntan na ni arin oru ọjọ ti o de si ile iya rẹ.

Aguntan, ti o fẹran awọn ọmọ rẹ pupọ, pinnu lati gbẹsan lara adan fun ona iwa ika ti o fi ebi pa ọmọ on. Nitorina o pinnu lati lọ sọ fun alabahun, nitori gbogbo enia li o ka a si ẹni ti o gbọn julọ ninu gbogbo awọn ẹranko bi kotilẹ ni ono.

Lẹhin igbati aguntan ti ro ẹjọ fun Alabawun tan, o ronu fun igba diẹ o si sọ fun aguntan pe ki o fi ọran na le on lọwọ ati pe on yio gbẹsan lara adan nitori ilọkilo ti o lo ọmọ aguntan.

Ko pẹ lẹhin eyi ni adan tun pinnu pe on yio lọ ki ana on nitorina o tọ aguntan lọ o si bẹ ẹ pe ki o fun on ni okan ninu awọn ọmọ rẹ lati ru ẹru on gẹgẹbi ti Işaju. O wa jẹ wipe alabahun wa nibẹ nigbati o si sọ fun adan wipe on pajọ nlo si ọna ibẹ ati wipe on yio fi tayọtayọ ru ẹru rẹ.

Ni ọjọ keji, nwọn bẹrẹ irin ajo wọn nigbati nwọn si de ibi Işaju, ni idaji ọna adan şe gẹgẹbi o ti şe fun aguntan ni ijọsi o sọ fun alabahun lati fi iwo rẹ pamọ si abẹ igi ti ọmọ aguntan fi pamọ si ni ijọsi Alabahun si şe bẹ şugbọn nigbati adan ko wo ọdọ rẹ o he iwo omi na o si ku bo apo rẹ, Nigbati nwon de ile ti nwon nlo alabahun fi iwo na ko si agbala nibiti ẹnikan ẹnikan ko gbe le ri i, o si lo joko ninu ile nigbat o ku diẹ ki akoko onjẹ to adan ran alabahun lati lo mu iwo omi na.

(Koiti pari)

# ELETI - OFE

A-NJU-WỌN KO ṢE WI L'ẸJỌ

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM

28, Kosoko Street, Lagos. "ELETI - OFẸ LAGOS"

P. O Box 468 Phone 23370

VOL. XL. NO. 647. SATURDAY OCT. 31 - NOV., 6, 1959.


## Ofin Alatia Fun Gbogbo Enia

Gẹgẹbi aṣeyọri iṣẹ ikede idibo ti Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ nṣe kakiri ilẹ Nigeria ti o kun fun idilọwọ nilẹ Ariwa (Oke-Ọya) ti awọn Hausa ko fi aye silẹ fun Oloye Awolọwọ lati ba awọn ara ilu sọrọ ati lati ṣe alaye ohun pataki ti ẹgbẹ Afẹnifẹre (Action Group) ngbero lati ṣe fun wọn ki nwọn le bọ lọwọ igbekun ijọba ilẹ Hausa, nigbati awọn ẹgbẹ ti ijọba na mbẹ lọwọ wọn ti mọ amọdaju wipe bi awọn enia ba le gbọ ọrọ ẹgbẹ Afẹnifẹre, laisi ani-ani, awọn yio kọ ẹgbẹ Olomi silẹ.

"Ofin Alafia Gbogbo enia" ti aṣiwaju ẹgbẹ Afẹnifẹre ti nkigbe rẹ lati ọjọ jọjọ yi wa, ni eyiti a gbọ wipe o ti wọ inu iwe eto iṣelu ilẹ Nigeria nilu Oyinbo, o si ti bẹrẹ si ṣiṣẹ lati ọjọ kẹrinlelogun oṣu October, 1959, yi. Eyi jẹ ọkan pataki julọ ninu iṣẹ aṣeyọri ti aṣiwaju ẹgbẹ Afẹnifẹre ṣe ninu irin igboke-gbodo rẹ fun ikede idibo ijọba apapọṣe ti o mbọ ninu oṣu December l'agbara Edumare.

Nitorina, iṣẹ ti aṣiwaju ẹgbẹ Afẹnifẹre ati awọn isọngbe rẹ ti nwọn jẹ igi lẹhin ọgba ninu ẹgbẹ na nṣe fun rere ilọsiwaju ilu wa yi ko ṣe f'ẹnu sọ tan.

Ẹ DIBO FUN ỌPẸ

## Awon Ara Ile Mauritius Nilu Oyinbo




Awọn ti a nwo ninu aworan yi ni awọn Iko lati ilu Mauritius, nigbati nwọn gunlẹ si ilu Oyinbo lọ ṣe eto ilu wọn. Orukọ wọn lati oke wa sile :- Ọgbẹni R. Sinifasin, DR. Ramgulam, Dọkita L. A. Sẹlẹstin, A. G. Sausia, J. M. Koenig, A. R. Mohamed, J. G. Forget ati J. G. Rosimọnt.

Ẹniti o duro niwaju wọn ni Sir Robert Scott.







# Awon Omo Ile Hausa Nilu Oyinbo



Awọn obinrin to duro ti a nwo yi ni awọn obinrin ile Hausa ti o nse ise itoju ilu, ti awọn ko lọ lati wo bi ilu Oyinbo Gẹsi ti ri. Ẹniti o duro ni arin meji wọn ni Lieut-Col. R. H. Creasy, Bale Mayor ilu Exeter ati iyawo rẹ.

Awọn alejo nwọnyi nilu Exeter ni nwọn de si, Bale ilu na lo si gba wọn ni alejo. Lasiko ti nwọn wa nilu Oyinbo, o mu won lọ wo ibiti awọn obinrin gbe osise, gẹgẹbi Orthopaedic Hospital ile alabiyamọ (Maternity Home) ati ibiti awọn obinrin gbe nṣe iṣẹ agbẹ.

## Aboyun Osin Ji Omolomo Gbe Salo

**ENUGU.** A gbọ irohin wipe, obinrin kan di aṣọ mọ inu gẹgẹbi eyiti o ni oyun, o wa siie alabiyamo fun itọju, nwọn si gba sibẹ gẹgẹbi aboyun.

Lọjọ keji ti o de ibẹ, ni o gbe ọmọ titun kan ti nwọn ṣẹṣẹ bi, ti iya rẹ bọ si baluwẹ. Olutọju ile alabiyamọ na tete yara kebosi lo ba awọn ara abule ibiti nwọn kọ ile alabiyamo na si, awọn ara abule na dide, won si tọpasẹ aboyun ọsin na lọ, nwọn si ri mu, nwọn mu lọ si kotu ibilẹ ibẹ ni nwọn ti ju si ẹwọn oṣu mẹfa, nwọn si gbe ọmọ fun ọlọmọ.

Nibiti nwọn gbe arojo ninu kotu, ibẹ ni aṣiri ti tu wipe aboyun ọṣin na ko ni oyun rara, aṣọ lo ndi mọ nu kakiri ki awọn enia le wipe o loyun.

A gbọ wipe oro yi ko mọ niwọn, okun inu awọn igbimọ ile na so pe on ko fi ara mọ ona ti kotu ibilẹ fi da ẹjọ na he, nitoripe nwọn ko wadi wo ki nwọn to daa ni ẹbi. Awọn ọlopa ijọba nṣe iwadi oro yi lowo lodo awọn adajọ to da ẹjọ na lati le gbe ẹjọ na yọju si oyinbo Ajele kotu Okigwe. Ẹnu ẹjọ na ni nwọn si wa.

## BABA ẸGBẸ IGBOMINA PARAPỌ JARE ẸJỌ RẸ

ILỌRIN. Okunrin kan ti a npe ni Malam Momodu Jokotọla ti a gbọ pe, on ni Baba ẹgbẹ awọn Igbomina Parapọ ni Ilọrin.

Okunrin na ni nwọn fi sun ẹsun wipe on pelu okunrin kan ti nwọn npe ni Israel Aremu lo jijẹ lọ fun okunrin Aṣogbo kan ni owo abẹtẹlẹ poun kan. kotu Ilorin si gbe awọn mejeji ju si ẹwọn. Ṣugbọn awọnenia na so wipe, nwọn ko ni itẹlorun si ẹjọ ti nwọn da fun wọn, awọn si gbe ẹjọ won lọ si kotu kotẹmilorun.

Awọn eni mejeji na gba Oloye Abiodun Akerele ni Loya, o sọ fun adajọ wipe bi o ba jẹ wipe lotitọ ni awọn enia na fun okunrin Aṣogbo na ni owo ẹhin, a ko gbọ wipe oniṣẹ ọba ni Aṣogbo na, beni nwọn ko si ro mọ ẹjọ pe oniṣẹ ọba ni.

Ni adajọ ba da Momodu Jokotọla ati Israel Arẹmu silẹ pe ki nwọn ma lọ ni alafia.

## A KO FẸ KI FARANSE YIN ETU OLORO NA

BOMBAY. A gbọ irohin wipe awọn enia tiṣe ẹni ti a bi nile Afrika ti o ngbe ilẹ India sopanpa, nwon si kọ ara won jọ lati lọ ka aṣoju ilu Franse mọle lati fi ọrọ ẹdun won han nipa ohun ti nwon ko fẹ ki Franse ṣe silu won.

Bi nwọn ti nlọ sile aṣoju ilẹ Faranse na, ni ọlọpa pade won lọna, o da won duro o bere kini nwon nba lọ sile aṣoju na (French Consulate) lẹhin ti o ti gbọ ohun ti nwon mba lọ sibẹ tan, o dahun pe, nje bi o ba je pe eyi ni ohun ti nwon ba bọwa ko nṣe gbogbo awọn enia nwonyi lo kuku ni lati yọju si Aṣoju na tan.

Nitorina ki nwon yan awọn enia mẹta pere lati lọ ba aṣoju na sọrọ nipa ohun ti nwon fẹ. Nigbati awọn enia na dewaju aṣoju na nwon wi fun ọ, lati yin ibon atọm, ohun ere lo je fun Faranse, ṣugbon iku lo je fun wa nilẹ Afrika, a ko fẹ ki Faranse yinbọn etu oloro na.

E MA KA
IWE IROHIN
ELETI-OFE
LOSOSẸ
O KUN FUN
IROHIN ALADUN

No 154

# Irun Odun Ninu Mosalasi Ilu Oyinbo



Awọn obinrin meji ti o duro ti a nwo ninu aworan yi ni awọn ọmọbinrin ara ile India meji ti nwọn kirun ninu Mọsalasi kan ti o wa ni adugbo kan ti a npe ni Woking nilu Oyinbo. Irun ọdun Ileya ni nwọn lọ ki, nigbati won jade si ẹnu ọna Mọsalaşi ni nwọn ya aworan yi.

# Federal Elections

## Powers Of Polling Agents

Under Regulation 63 of the Electoral Regulations each candidate is allowed to appoint two persons to attend at each polling station in the constituency for which he is a candidate and these persons are referred to as Polling Agents.

The Regulation also provides that the powers of Polling Agents may be laid down by the Electoral Commission. The Commission has decided that no further powers should be given to Polling Agents in addition to those which are already conferred upon them by the Regulations.

These powers are :-

1 To be present in the polling station througout the hours of poll (Regulations 63 and 85).

2 To look at the ballot boxes inside the polling station immediately before they are locked and sealed, to see that they are empty, that they are duly marked with the name and symbol of the candidate and that his photograph is displayed, if it has been provided, and to see that they are fixed inside the voting compartment in accordance with the Regulations before polling starts (Regulation 66 (3).

3. To watch the polling officer opening the sealed packets of ballot papers and to inspect them (Regulation 66 (3).

4. To see each ballot paper to be marked with the official mark before it is issued to the voter (Regulation (68 (a).

5. To require a polling officer to put to a voter applying for a ballot paper the following questions :

(a) "Are you the person who is on the Register of Electors as follows. . . . . . . ?"

(b) "Have you already voted at the present Election at this or any other polling station ?"

(REGULATION 69)

6. To declare to the Presiding Officer at any time when a person applies for a ballot paper or after he has applied but before he has left the polling station that he has reasonable cause to believe that the applicant has committed an offence of impersonation. If a Polling Agent makes such a declaration, he must sign an undertaking in writing to substantiate the charge in a Court of Law and the Presiding Officer may then order a Police Officer to arrest the applicant. (REGULATION 81)

7. To be present after the close of poll while the Presiding Officer seals the ballot boxes and makes up the packets referred to in Regulation 89 (REGULATION 89 (1)

8. To verify the ballot papers account prepared by the Presiding Officer. If a Polling Agent does this, he must then sign the account. (REGULATION 89 (4)

A candidate has all the powers of a Polling Agent. (REGULATION 63)

The Electoral Commission wish to make the following two points quite clear:-

(a) Although a Polling Agent has the rights set out above, he is not entitled to interfere with the conduct of the poll and if he misconducts himself or fail to obey a lawful order given by the Presiding Officer, the Presiding Officer has been instructed to order him to be removed from the polling station.

(b) Although Polling Agents have the RIGHT to be present, their presence is not ESSENTIAL and in no circumstances will the conduct of preceedings be delayed because a Polling Agent is not present. If a Polling Agent is absent before the opening of a polling station when the Presiding Officer is sealing and locking the ballot boxes and opening the sealed packets of ballot papers, the Presiding Officer will not wait for him. If a polling Agent is absent at the close of poll when the Presiding Officer is ready to seal the ballot boxes and the other packets referred to in the Regulations, the Presiding Officer will proceed to do this without him.

## Adajo Agba So Agbeje Mo Alikali Nidi

ILỌRIN. Adajọ agba ati adajọ kotu Ganran meji lo joko se ẹjọ Malam Ahmadu Elemẹre ti o jẹ Alikali (Adajo) kan ni agbegbe Ilorin ti nwọn si da lẹbi.

Ohun ti a gbọ wipe Alikali na şe ni wipe ni asiko ti o mbẹ lori atẹ idajọ, o paşẹ fun ọlọpa ilẹ kan, Malam Aruna wipe, ki o lọ gba ọkunrin kan ti o jẹ ọmọ ẹgbẹ Action Group le'i ni arin Kotu.

A gbọ wipe awọn ọmọ egbe yi ba Alikali na şe ẹjọ niwaju kotu kekere, adajọ kotu na sọ pe Alikali na ko jẹbi, ki o ma lọ.

Ẹgbẹ Action Group dahun pe, ẹjọ yẹn ko tẹ wọn lọrun, ni nwọn ba gbe ẹjọ na lọ si Kotu ẹjọ Kotẹmilọrun.

Adajọ kotu Kotẹmilọrun sọ pe, gẹgẹbi ofin ati ni gasikiya Alikali na jẹbi, nitorina ki o lọ so agbeje mọ idi fun ọdun kan ti ọrọ rẹ ko gbọdọ de kotu mọ.

## ADABA NFOGEDE O ṢEBI ẸIYẸLE KO GBỌ

Lati ọwọ Ẹsọ

Nigbakan, Aparo, Adaba ati Ẹiyẹlẹ jijọ nṣe ọrẹ. Ẹiyẹle pe awọn mẹtẹta o ni ẹ jẹki a lọ mule si odo awọn enia nitoripe, ibẹ lo le rọwa lorun, gbogbo wọn gba lati ṣe bẹ, nwọn silọ gbe ọdọ enia

Ẹniti ẹiyẹle ngbe ọdọ re di aṣọ mẹta funu d du funfun ati pupa ẹniti Aparo ngbe ọdọ re ko jẹki aparo jade si ode, o si fi ebi pa a.

Ẹniti adaba ngbe ọdọ re jẹ Agbẹ, eso igi oori lo si nfun adaba jẹ.

Nigbati adaba ri pe ibẹ ko bẹ su ọ fun on, o jade lo gbe ọdọ ẹlomiran ti o tun jẹ Agbẹ, isu egbodo ati ewura ni eleyini ngbin. Nigbati eleyini nfi ebi pa adaba, bẹ lo ri agoẹ miran ti o gbin e o bara (Ẹgusi).

Bi ẹiyẹle ba nfo koja lọ bi ap ra ba ti g ro re yio m [illegible] jokalẹ jokalẹ jokale

B adaba [illegible] bere si ṣe [illegible] pe : Mi o o jori [illegible] o jori titi mi o jori titi Elegbodo ko ku elegbodo ko ku onibara ko ye onibara ko ye onibara ko ye.

(Koiti pari)


**HINDU SANKARA'S**

**Religious Art Jewelleries**



Perfumes, Charms, Mohammedan charms, Amulets, Vedic Prayer Kawachas, Faithful Reproductions of Hindu Gods in the Jewelleries.

*Enclose 4/- Postal order by Air Mail for Catalogues and Literature.*

**HINDU SANKARA, 431 Archway road, London, N.6. England**


## IYE AWỌN JAMBA TO ṢẸLẸ LỌNA ỌYỌ

**IBADAN.** Irohin tẹ wa lọwọ wipe jamba mẹtalelogojilerugba to ṣẹlẹ larin Ibadan lọ si Ọyọ, larin meji ibẹrẹ oṣu july si ipari oṣu September 1959.

Mẹrinlelogun ninu jamba na lo jasi iku, mẹtadilogoji lo le pupoju. Ṣugbọn awọn ti nwọn fi ara pa ati awọn to fi ara ṣeṣe jẹ 227.

Nigbati awọn ọlọpa fi ara balẹ wadi kini eredi jamba wọnyi, nwọn wipe, 134 ninu awọn jamba na jẹ aibikita fun emi enia lati ọwọ awọn dẹrẹba mọto. Ara mọto ti ko murọ fa sababi mẹrindinlogun, ere asaju fa jamba adọta mọto ati wipe aiko wo ọtun, wo osi ki awọn enia to re koja fa jamba mọto mẹtalelogoji.

Awọn dẹrẹba ti ijọba ba ṣe ẹjọ, enia mọtadilogoji lo jẹbi, ẹjọ awọn yoku ṣi mbẹ ni kotu niwaju adajọ.


" The English Association of Accountants & Auditors. The English Association of Estate Agents & Valuers. The English Association of Secretaries. Founded 1941. Membership on Professional Experience (Give Details) or Exams passed. 9, Charles St. Newport, Mon. Eng".








## Kẹrẹ o !

A ni oriṣiriṣi ogun German to ṣẹṣẹ de, fun oniruru aisan tọkunrin tobinirin. Tete wa ra tirẹ ki o to tan.

**J. A. AJAO BROTHERS**

**MEDICINE STORES**

**7, Egerton Road Lagos**

## KINLA! NWỌN TUN NJE ENIA NILU SARO?

FREETOWN. A gbọ irohin wipe, awọn ọkunrin mẹfa kan ki ọmọ ilewe kekere kan ti ko ju ọmọ ọdun mejidilogun lọ mọlẹ, nwọn gbe lo sinu igbo nibẹ ni nwọn ti lupa nwọn fa irun ori rẹ. awọn ko sinu apoti kan, awọn ge ori rẹ si ọtọ. Nwọn si ẹran ara re, nwọn fi se iresi je. nwọn si gba ẹjẹ ara ọmọ na sinu awo koto kan.

Lẹhin ti nwọn pari jijẹ ẹran ara ọmọ na tan, awọn gbe ori rẹ, egungun rẹ wọn lọ dana sinu okun. Awọn enia mefa ni awọn ọlopa ranu fun ẹsan apania na.

Ọkan ninu won ti o njẹ Joe Bọli, ti o ngbe abule kan ti nwọn npe ni Mania ni adajọ da silẹ ni alafia nitoripe ko lowo ninu pipa omo na, o wa ku awon marun. Ninu awon marun ti o ṣeku okan ninu nwon ku si ogba ẹwon o ku awon mẹrin.

Oruko awon merin ti o ku ti nwon o yẹgi fun nwonyi: Fonle Sesay Beah Charlie Hampa Ndefal ati Kenel Charlie.

## EṢE TI IJỌBA PA ILEWE GBAGIMỌLẸ RẸ?

Ijọba ti kọ ilewe kan si ilu Ibadan nibiti nwon gbe nkọ enia ni iṣe gbagimọlẹ (Survey School). Ẹniti nwon ba kọ nibẹ ti o si yege, lati ibẹ ni yio ti di wonlẹ-wonlẹ ti o ni aṣẹ lati wonlẹ fun enia, ṣugbon ijọba ti wo ilewe na lule

A ko mọ kini sababi ti ijọba ri ki nwon to fi opin si ilewe na, nitoripe ibẹ ni a gbe ti gbe awon wonlẹ-wonle wa dide. A ko gbọ wipe, wonle-wonlẹ kan ti nwon kọ ninu ilewe yi, ti o jade ti ko mo iṣẹ na yekeyeke ti wa ri.

Ara awon wonlẹwonlẹ ti won ti nṣiṣẹ gbagimọlẹ kiri ti nwon kọ ti o si jade ninu ile iwe na ni ologbe Bucknor, ati J. A. Brown, ti nwon ṣiṣẹ de ipo igba keji oga agba, jẹ ẹniti nwọn kọ ninu ilewe na.

Ogbẹni Gascoin, ti o jẹ igbakeji oga agbegbe Iwọ Orun jẹ eni ti a kọ nibẹ pelu. Ogbeni Wey oga agba nile Hausa, ibẹ ni a ti kọ nọẹ wonlẹwonlẹ.

## IYE OLỌPA TI YIO ṢIṢẸ NIGBA IDIBO NLA

(O bere loju ewe kini)

yan, 7.500 ni iye ibiti nwon o gbe apoti idibo si. Ni Eko, enia meta ni nwon fe dibo yan, 300 ni iye ibiti nwon o gbe apoti idibo si.

35 Million ni iye awon enia ti o mbe nile Nigeria ṣugbon 9,030,000 ni iye awon enia ti yio dibo na.

Morteages on all classes of properties, write for particulars:

Spencers (506)
Spencer House, Cambridge Road, London N. W. 6. England.

E MA KA
IWE IROHIN
ELETI-OFE
LỌSỌSẸ
O KUN FUN
IROHIN ALADUN

## Omo Oyekan Di Alabase Po Pelu Egbe Afenifere




Ẹniti a nwo yi ni Adeyinka ọmọ Oyekan, ẹniti awọn ọmọ Ọba Dosunmu yan sode lati role baba wọn, nigbati awọn ara ilu Eko nfe Musẹdiku Adele ti o si titori eyi di ota ara Eko, nigbati o wipe ki Musẹdiku jade kuro ni Iga. Ṣugbọn Ọmọba Oyekan na, tete de oju rẹ silẹ o ri wipe, awọn ti o jẹ alatilẹhin fun on ko to gbe ojule, o pada lẹhin wọn o si fi ara mọ eto ẹgbẹ Afẹnifere, nigbati ẹniti a wipe ki o kinni lẹhin fi ẹgun si ọwọ ti ẹniti a pe ko fẹni loju fi ata senu.

Loni Omọba Oyekan ti a wi na ni a nwo ninu aworan yi, o ti tun pada di ọrẹ ara eko, nipa fifi ara mọ eto ẹgbe Action Group.

## E Jowo Fi Idi Oro Nwonyi Ye Wa

Olotu,

Jowo gba mi laye ninu iwe irohin re oloyin mọmọ kin fi idi gbolohun nwonyi?

1. A mo wipe ijoye ilu ni oye Balogun, kilofa ti a fi npe eniti a ko fi joye rara ni Balogun gegebi nwon ti npe gbogbo eniti o ba je Alli ni Balogun, opo ninu awon ti a mo ni Balogun ilu oruko won ko nje Alli.

2. Kini idi re ti nwon fi npe gbogbo Lawani ni Amubi-oya, kini itumo Amubi-oya paapa?
3. Kini idi rẹ ti nwon fi npe Ojo ni Baba aladiẹ tabi ti nwon nki bayi pe, okina-kina, otoju aladie ki e sina?
4. Kini tije ti nwon fi npe gbogbo Salami ni Agbaje?
5. Kilofa ti nwon fi npe awon ti o ba nje Ahmodu ni Ejalonibu?

Emi ni
Alhaji Jenmi.

## Ogun Aran ejo Inu




Aradan Worm Expeller je ogun aran pataki fun ọmọde ati agba ọkunrin ati obinrin. Ra igo kan lati ya gbogbo awọn aran buruku ti o nba ọ ja ninu danu. Bi o ti npa aran bẹni o npa ẹnyin wọn. Wa ra tirẹ ki o to tan. Igo kan jẹ 2/6
Owo ọkọ si jẹ 1/.
THE ẸGBA TRADING
ARADAN STORES
18, Denton Bridge Street.
P. O. Box 2. Ebute Meta

Printed & Published by The Union Printing And Publishing Company 28, Kosoko Street, P.O. Box 47 Lagos, Phone 23370.